# HAMANI ȘUBU NINU IDẸKUN ARA RẸ̀

**Ẹsteri 3:1-15; 4:17; 5:1-14; 6:1-14; 7:6, 9, 10**

**ẸKỌ 430 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Igberaga ni iṣaju iparun, agidi ọkàn ni iṣaju iṣubu" (Owe 16:18).**

**Olootu Ijọba**

Lonii a o kẹkọọ nipa ohun ti o ṣẹlẹ si ọkunrin kan ti o jẹ eniyan ti o kún fun ibinu. Ọkunrin yii kún fun ero giga nipa ara rẹ, a si maa mu inu bi i, bi ẹni kan kò ba kà a si ẹni giga bi oun ti n rò ara rẹ si.

Hamani,(bẹẹ sa ni orukọ rẹ n jẹ) ni a ti gbe si ipo giga ninu ijọba Perṣia, ọba si ti paṣẹ pe ki gbogbo awọn iranṣẹ oun maa tẹriba ki wọn si maa bọwọ fun Hamani. Ọba naa, Ahaswerusi, n jọba lori igberiko mẹtadinlaadoje (127) lati agbegbe India titi wa de ilẹ Afrika. Hamani ni igbakeji ọba. Ṣuṣani, olu-ilu ni o n gbé, iṣẹ rẹ gẹgẹ bi olootú ijọba a maa mu ki o wá si aafin nigbakuugba.

Bi Hamanni ti n wọle ti o si n jade ni gbogbo awọn iranṣẹ ọba n tẹriba fun un ni ẹnu-ọna. Ṣugbọn ki i ṣe gbogbo wọn patapata. Ẹni kan wà, Ju kan, ẹni ti orukọ rẹ n jẹ Mọrdẹkai. A ti mu un lati Jerusalẹmu lọ si Babiloni nigba ti Nebukadnessari n ṣe akoso gbogbo ayé. Ni akoko yii ti Ahaswerusi jẹ ọba, a ti mu Mọrdẹkai wá si Ṣuṣani aafin. Lojoojumọ, bi Hamanni ti n wọle ti o si n jade ni ẹnu-ọna aafin, ni gbogbo eniyan n wolẹ ti wọn si n tẹriba fun un, afi Mọrdẹkai nikan ṣoṣo.

Lai si aniani, Mọrdẹkai ti gbọ́ Ofin Ọlọrun lojoojumọ ni ilu ibilẹ rẹ, o si ranti ofin ti o wi pe, "Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun miran pẹlu mi. . . .. Iwọ kò gbọdọ tẹ̀ ori ara rẹ ba fun wọn, bẽni iwọ kò gbọdọ sin wọn" (Ẹksodu 20:3, 5). O bu ọlá fun Ọlọrun, kò si tẹ ara rẹ̀ ba.

**Ikorira Gbogun ti Ọkan Didakẹ-jẹ́**

Wo bi eyi ni ti bi Hamani ninu tó! O kún fun irunu lọpọlọpọ. O korira Mọrdẹkai; nigbakuugba ti o ba si ji ni o n ronu bayii pe, Bawo ni emi yoo ṣe le pa Mọrdẹkai? Ero Hamani di kikoro gidigidi. O wi ninu ọkan rẹ pe, Emi o pa gbogbo awọn Ju, o si pinnu rẹ bẹẹ.

Iru ero bayii ni èṣu maa n ni lọkàn si olukuluku ẹni ti o n sin Ọlọrun. Eṣu n fẹ lati pa olukuluku run. Ṣugbọn Onigbagbọ́ ni ohun ija ti o daju. Bibeli wi pe: "Ẹ kọ oju ija si Èṣu, on o si sá kuro lọdọ nyin" (Jakọbu 4:7). Ojo ni èṣu, nigba ti Onigbagbọ́ kan ba fi igboya duro gangan fun ohun ti o mọ̀ pe i ṣe otitọ, eṣu yoo lọ kuro pẹlu itiju.

Otitọ ni pe gbogbo wa ni a maa n ri ohun ti kò tọ ninu igbesi-aye awọn ti wọn yi wa ká lati igba de igba, ṣugbọn gẹgẹ bi Onigbagbọ́ a ni lati kọ́ lati fi iru nnkan bawọnni le Oluwa lọwọ ki èṣu má ba gba isinmi ati idakẹrọrọ alaafia ti ani ninu ọkàn wa kuro.

**Eto Igbẹsan**

Hamani ṣaapọn pupọ lati wu ọba ati lati ri ojurere rẹ ki ọba ba le ṣe ohunkohun ti o ba beere lọwọ rẹ̀ fun un. Nisisiyii awọn ọrẹ Hamani pinnu ọjọ rere kan -- gẹgẹ bi wọn ti gbagbọ -- ti Hamani yoo sọ fun ọba pe awọn eniyan kan wà ninu ijọba rẹ ti kò fẹ lati pa ofin rẹ mọ́ ṣugbọn ti wọn n tẹle ofin ti ara wọn. Yoo si dara bi a ba pa wọn run ki a si gbá wọn kuro ninu ijọba Perṣia.

Lẹsẹkẹsẹ ni ọba fi ọwọ́ si i a si rán iṣẹ jade si awọn alakoso ni gbogbo igberiko ijọba Perṣia lati parun, lati pa, ati lati run gbogbo awọn Ju, ọmọde ati agba, awọn ọmọ ọwọ́ ati obinrin ni ọjọ kan, ki awọn ara Perṣia si jogun gbogbo ile ati ọrọ̀ wọn.

## Ibanujẹ

Nibi gbogbo ti a ka aṣẹ ọba ibanujẹ nlá nlà ni o mu wa. A kaa ni Ṣuṣani aafin pẹlu, Mọrdẹkai si fà aṣọ rẹ̀ ya o si fi aṣọ ọ̀fọ si ara rẹ, o si fi eeru kun ori rẹ, o si jade lọ si aarin ilu naa, o si sọkun kikan ati kikoro.

Nigba ti Ẹsteri ranṣẹ lati wadii ohun ti o fa ibanujẹ nla-nla ti o de ba Mọrdẹkai arakunrin baba rẹ, Mọrdẹkai fi akọsilẹ aṣẹ Ọba naa ranṣẹ si i, o si wi fun un pe ki o tọ ọba lọ, ki o si bẹbẹ fun aanu lọdọ ọba fun awọn eniyan rẹ, awọn Ju.

**Ifẹ ati Ibẹru**

Ẹsteri bẹ̀ru lati tọ ọba lọ. Ọba kò ranṣẹ si i fun ọgbọ́n ọjọ sẹyin bẹẹ ni oun kò si le sọ boya ọba tilẹ bikita fun oun mọ́. Bi ko ba na ọpa-alade wura rẹ̀ si i, a o pa a. Mọrdẹkai tun ranṣẹ si Ẹsteri pe, "Máṣe rò ninu ara rẹ pe, iwọ o là ninu ile ọba jù gbogbo awọn Ju lọ. Nitori bi iwọ ba pa ẹnu rẹ mọ́ patapata li akoko yi, nigbana ni iranlọwọ ati igbala awọn Ju yio dide lati ibomiran wá; ṣugbọn iwọ ati ile baba rẹ li ao pa parun: tali o si mọ̀ bi nitori iru akokò bayi ni iwọ ṣe de ijọba?"

Olukuluku eniyan ni akoko anfaani lati ṣe ifẹ Ọlọrun maa n dé bá. Anfaani ni ilẹkun ti o maa n ṣi silẹ lati ṣe ohun gbogbo ti o jẹ rere ni ayé. Bi a ba fi ilẹkun yii silẹ ni titi, a fi ẹmi wa ṣòfo ni, bẹẹ ni ibukun ti awa i ba jẹ fun awọn ẹlomiran ki yoo kún aye wọn tabi ti wa.

**Adura ati ifayabalẹ**

Ni akọkọ o wi fun Mọrdẹkai ati awọn Ju ti o wà pẹlu rẹ ni Ṣuṣani pe ki wọn gbaawẹ ki wọn si gbadura fun ọjọ mẹta lọsan ati loru, oun ati awọn ọmọ-ọdọ ti o wà lọdọ rẹ yoo gba aawẹ ati adura pẹlu. Lẹyin adura ọjọ mẹta yii Ẹsteri ti ni lati ni idaniloju pe ifẹ Ọlọrun ni i ṣe yala oun yè tabi oun kú. Bi o ti n wọṣọ ayaba rẹ lati lọ si iwaju ọba bi o ti joko lori itẹ rẹ, ọkàn rẹ ni lati maa ṣiṣẹ bi aago pẹlu ireti ni pe ọba yoo na ọpa-alade wura rẹ jade, ati pẹlu ipinnu pe oun yoo kú pẹlu igboya, bi ọba ba paṣẹ ni ibinu rẹ pe ki a pa oun.

Ayaba Ẹsteri ni ireti pe a o dá awọn ẹgbẹẹgbẹ̀run Ju igbekun silẹ kuro ninu ẹbi ikú, oun si ṣetan lati fi ẹmi rẹ lelẹ ki awọn wọnyii ba le là.

**Iye dipo Ikú**

Ọpọlọpọ ọfọ, tabi ibanujẹ, ni o maa n wà nigba ti ẹ̀ṣẹ tabi iwa buburu ba wà yika. Ṣugbọn dajudaju, a ni lati ṣe eyi ti o ju pe ki a maa ni ibanujẹ nipa rẹ lọ! A ni lati lọ si iwaju Ọlọrun, Ọba nla ni ati Alakoso gbogbo aye, ki a si gbadura pe ki O dá ẹmi awọn ẹlẹṣẹ si, ki O rán Ẹmi Mimọ́ lati bá wọn sọrọ nipa ẹ̀ṣẹ wọn, nipa ikú Jesu lori Igi Agbelebu fun wọn, ati nipa idajọ ti n bọ wá si ori wọn bi wọn kò ba ronukpiwada.

A ni lati mura tán, gẹgẹ bi Ẹsteri ti ṣe, lati fi ẹmi wa paapaa lelẹ ki awọn ẹlomiran ba le là. Ọ̀kan ninu awọn alufaa wa n sọ nipa igba ti oun ni ipè ninu ọkàn oun lati lọ si Afirika lati lọ tan Ihinrere kalẹ nibẹ. Eyi yoo gba pe ki o fi iya ati baba rẹ silẹ, pẹlu ọmọbinrin rẹ kekere, awọn olufẹ ati awọn ọrẹ rẹ ni Amẹrika. Ṣugbọn o ti mura tan lati ṣe e. Boya o ti kà nipa ajihinrere Livinstone ẹni ti o fi ile rẹ ni England silẹ lati wá si Afirika ti o kún fun okunkun, lati sọ fun awọn olugbe ibẹ nipa igbala. O jère ọpọlọpọ ọkàn fun Jesu nikẹyin o si fi ẹmi rẹ lelẹ ni Afirika.

A le ṣe alai pè ọ lati lọ si ọna jijin bi ilẹ Afirika tabi Japan, ṣugbọn Ọlọrun ha fi si ọ ni ọkàn lati sọ fun ọrẹ kan tabi olubaṣire rẹ kan nipa igbala, lati fun ni ni iwe ihinrere, tabi lati pe ẹni kan wa si ile Ẹkọ Ọjọ Isinmi, iwọ ko gbọdọ fasẹyin nitori ibẹru pe awọn kan yoo fi ọ ṣe yẹyẹ tabi ki wọn ṣe iwọsi kan si ọ. Tootọ ni pe awọn kan ki yoo jẹ ipe naa ṣugbọn ẹni kan le wá; bi iwọ ba si jere ẹmi kan fun Jesu, eleyi ni to fun gbogbo wahala rẹ.

**Ikorira jẹ́ Ẹrù wuwo**

Ọlọrun ti dahun adura, bẹẹ ni ọkàn ọba si fà lati gba Ẹsteri. Ṣugbọn ni gbogbo akoko yii Hamani ni ikorira Mọrdẹkai ni ọkàn; nitori naa nipa amọran awọn ọ̀rẹ rẹ, o ri igi isorọ̀ kan ti o ga mọlẹ lori eyi ti o fẹ́ lati so Mordẹkai rọ̀ si. Bi ẹni kan ba ni ikunsinu si ẹlomiran, ẹni naa yoo ri ẹni kan ti yoo gba a niyanju lati tubọ kun fun odi si i, titi yoo fi sọrọ tabi ki o ṣe ohun ti o koro tabi ti o kún fun ikorira si ẹni naa.

Ini-nisinu jẹ ẹrù kan (o maa n mu ki ọkàn eniyan wuwo) ti Ọlọrun kò fẹ ki ẹnikẹni rù. O mọ̀ pe nikẹyin iwuwo naa yoo fa ọkàn oluwarẹ lọ si ọrun apaadi bi ko ba ronupiwada ki o si kọ ọ silẹ. Nitori naa Ọlọrun paṣẹ fun awọn eniyan rẹ lati maa dariji. Olukuluku Onigbagbọ́ ni o ni lati dariji bi o ti wu ki

ibi ti a ṣe si i ti le pọ to. O ni lati dariji bi ko ṣe bẹẹ Ọlọrun ki yoo dariji i (Matteu 18:23-35). Ọlọrun ni Ẹni ti o n jẹ eniyan ni iyà, ṣugbọn ipa ti Onigbagbọ́ ni lati fẹran ọmọnikeji rẹ̀ ki o si sin Oluwa pẹlu ọkàn ayọ̀ (Romu 12:19).

**Gbigbin ati Kika Eso**

Nitori naa a mu ibeere Ẹsteri fun igbala awọn eniyan rẹ̀ ṣẹ, ṣugbọn Hamani tikara rẹ̀ ni a sorọ̀ sori igi ti o ti pese silẹ fun Mọrdẹkai. Dipo ti a ba fi pa awọn Ju ki ile awọn ati ọrọ̀ wọn si di ti Hamani ati awọn ọrẹ rẹ̀, bi wọn ti n reti, Hamani ni a pa ti a si fi ohun-ini rẹ̀ fun awọn Ju.

Bi o ba fi akoko rẹ ati ipa rẹ lelẹ ki awọn ẹlomiran ba le ri igbala, iwọ yoo ni inu didun nihin; bi o ba si jẹ oloootọ, ère n duro de ọ ni Ọrun. Bi o ba n ro ibi si ẹlomiran, ibi yii gan an le wa ṣẹlẹ si ọ. Bi o ba ni eniyan ninu, iwọ yoo gba ère idalẹbi fun ẹlẹṣẹ nihin; bi iwọ ko ba si ronupiwada, idalẹbi ọrun-apaadi ni yoo jẹ ère rẹ lẹyin ayé yii.

"Ki a máṣe tàn nyin jẹ; a kò le gàn Ọlọrun: nitori ohunkohun ti enia ba funrugbin, on ni yio si ká" (Galatia 6:7).

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni orukọ ijọba Ahaswerusi?

2 Ta ni i ṣe olootu ninu ijọba rẹ̀?

3 Ki ni ṣe ti Hamani fi kún fun irunu nla si Mọrdẹkai to bẹẹ?

4 Ki ni Hamani pinnu lati ṣe si Mọrdẹkai ati gbogbo awọn Ju ni ijọba Ahaswerusi?

5 Ki ni Mọrdẹkai ṣe nigba ti a pa aṣẹ naa pe ki pa gbogbo awọn Ju?

6 Ki ni Ayaba Ẹsteri n fẹ ki Mọrdẹkai ati awọn Ju ti o wà pẹlu rẹ̀ ṣe ki o to lọ si ọdọ Ọba lati lọ beere fun aanu?

7 Ta ni a gbọdọ tọ̀ lọ lati beere aanu fun awọn ẹlẹṣẹ ninu ayé yii?

8 Ki ni ṣe ti a ni lati ṣe tán lati lo akoko ati aapọn lati ṣe iranlọwọ fun awọn eniyan lati ri igbala?

9 Ki ni ṣe ti awa Onigbagbọ́ ni lati maa dariji awọn eniyan, ki a má si ṣe ni ohukohun rara ni inu si ẹnikẹni?